**Owe**

Adie iba l'oko, iba l'atitan se akan. Imado iba je ti elede a ba'la je. Ero iba l'oba, enia ko ba ti ku okan.

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO ... EJO

**Asoje**

Enia ma leki l'enia sunwon, eni ma sun-won ko ni gbo. Ana omode ko ... iri Oro, ... doyika.

VOL. XIII No 682. LAGOS. SATURDAY JANUARY 28 — FEBRUARY 3, 1961 KOBO MEJI (2D)


# KOSI IBITI ESE 'OSI, TILU ILORIN L'OPELEKE.

ILORIN – Irohin agbo rerin fidi jale ti a gbo lati ilu Ilorin je iyanu fun opo enia, ko si le ya awon opolopo enia lenu nitoripe nwon ti o amodaju wipe ilu ti oja won ko je kun fun awon ti o nta oja losan bikose oru titi di oganjo, enikeni ti mo wipe kosi orisi ara ti nwon kole da nibe.

Irohin na ti a gbo nipe okunrin kan ti oruko re nje Audu Gombe, ara abule Ologbondoko, ni Aiwa obinrin re ti o je arewa enia so fun wipe on fe lo ki Kawu on ni'le Ilorin, ni Audu si lo wa isu ati awon nkan ti yio fi fun Kawu re bi o ba de ohun o si ko fun iyawo re.

Kia ma fa fa oro gun, a gbo pe iyawo mura o si lo si Ilorin, sugbon nigbati o di ojo keta ti iyawo ti lo, ti ko pada wale, ara Audu oko iyawo ko gba mo, on na mura, o wo aso agbada ti o dara o wa gbe ida re korun, o doriko ilu Ilorin. Nigbati o de ile Kawu iyawo re, asiko na ti di ojo ale, o wole, o ki won, awon na si ki o bere iyawo re, nwon so fun wipe o ba iyawo Kawu re losi oja. Oko iyawo joko sinmi die ki o to lo wo iyawo re l'oja ale.

Nigbati o de oja, o ba eniti iyawo re ba lo ni abe buka kan, nwon ki arawon, o fun ni aye lati joko, o si so fun pe iyawo re nibe ... iyawo na ni o ... gerete pelu okunrin ... lehin buka ti nwon ... ibiti nwon ti ... arawon.


ALHAJI SIR ABUBAKAR

## Olotu Ijoba Apapose Lo Be Ilu Ila-orun Wo

Olotu ijoba wa, Alhaji Sir Abubakar Tafawa Balewa lo be ile Ila-orun wo ni ojo kinnie-losun ... yi, yio si se to ojo meji ninu irin abewo re na ki o to pada wale.

(Wo yoku lo'u ewe kejo)

## T'egbon T'aburo Wewon

ONITSHA - Awon omo iya kanna meji ti nwon je t'egbon-t'aburo ni nwon je ole paraku, olopa mu awon mejeji de iwaju adajo ni Kotu ilu Onitsha.

Awon olopa fi awon mejeji sun esun ole jija pelu ipa, wipe nwon lo ji owo ati eru Ogbeni kan ti oruko re nje Emmanuel Awa ko ni Fegge, ni ilu Onitsha ninu osu October, tokoja.

Eru ti nwon ji ko na ati owo le ni igba posun, oruko t'egbon-ta'buro na nje George Egwu ati George Obi. Adajo sa won s'ewon odun meji meji fun enikokan.


THE NATIONAL BANK of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1938

Paid up Capital £1,130,000

Bankers to the Western Region Government of Nigeria

HEAD OFFICE

37, MARINA, LAGOS NIGERIA

22 Branches hroughout Nigeria Including IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.

LONDON OFFICE

1 THROGMORTON AVENUE, E. C. 2.

Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303

Cables & Telegrams Natbaniger London

Head Office Representatives in London

E. Akinwunmi Doherty,

CORRESPONDENTS

NEW YORK, PARIS HAMBURG.



ARADAN NERVIGORA



Ogun eje paraki fun Imarale agba ati ... fun awon alaya pupo. O dara fun inarun, eje dodo, isokun oju, ibigbon owo, ailesun, ailokun ninu ati irufe arun bawonni. O je aidewe fun awon ti agi ara won ... Oun na gan ni okunrin yi lo to fi di "Afese ku bi ojo". 5/6d pere pelu owo oko 1/6 eg. 7/- Post Free.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES
112, Denton Street, 15, Denton Bridge Street,
P. O. BOX 2, Ebute-Metta.

Phone 41153. A tun ... ni New Motor Park Ogunpa, Ibadan.

# KOTU GBA IDURO FUN OLAWONYIN

KADUNA – Ile ejo giga ti ejo arotunro Ariwa ni o gba iduro fun Ogbeni J.S. Olawoyin, omo egbe Afenifere fun ilu Offa ti o wa ninu ile igbimo Asofin ipinle Oke-Oya ni Ariwa, Kotu gba iduro fun Ogbeni Olawoyin pelu adota ponun ati eleri meji pelu iye owo bakanna.

Nwon ju Ogbeni Olawoyin sewon osu mefa ni Kotu ilu Ilorin ninu osu November, odun tokoja. Ninu Kotu kanna ni Oloye Rotimi Williams Q.C. ro ejo ti o mu Kotu fi ariyanjiyan nipa adajo ti o ni eto lati joko gbo ejo arotunro ranse si kotu nla ti Eko fun itosona.

## Igbimo Yio Gb'owo Lori Eran Pipa

IJEBU-ODE – Alase ilera ati alafia idaraya ilu, ti ijoba Iwo-orun ti gba wipe ki Ofin Eran pipa ti nwon se ni odun 1958, fun igbimo ibile ilu Ijebu-Ode bere si se ise.

Ofin na, nisisiyi o fun igbimo lagbara lati ma gba sile meje-abo (7/6) lori eran malu kokan ati sile meta (3/-) lori aguntan, ewure, ati elede ti nwon ba fe pa ni Ijebu-Ode ati agbegbe re.

# ILEWE ADITI SI SILE

IBADAN – Ilewe awon aditi enia ti o wa nilu Ibadan ni o ti si sile lati ojo Jimo ( Friday ) ojo kerindi-logbon osu yi, gegebi ilewe awon omode gbogbo ti bere ise won.

Awon omo ti o je aditi enia ti nwon ti ko ba si ilewe na je merin-le-logota, (64) e n g e b i Ogbeni Andrew Foster, Oludasile ilewe na ti wi. O tun so wipe oro owo ti nwon se ikede re ni asiko ominira wa ninu osu October tokoja mu £25 6 : 11-/ wa.

Ogbeni Anderw Foster tun kesi gbogbo enia fun iranlowo lati ma mu awon aditi omo wa si ilewe won.

# GOMINA FI IPILE LELE

Ojola nla, Gomina ipinle Iwo-orun, Sir Adesoji Aderemi ni fi okuta ipile ilewe giga tilu Modakeke leba Ife lele, o si fun won ni adota ponun (£50) nibi ayeye ifipile lele na ni ojo kerindi-logbon osu December, 1960.

Sir Adesoji yin awon enia Modakeke fun emi isokan ati iranra eni-lowo ti nwon ni, eyiti o so wipe o mu ero won yori si rere.

O si ba awon alase ilewe na soro wipe ki nwon jeki eko ile se pataki, eyi ni yio mu awon omo akeko to bi a ti npe won, ati igberaga fun Ominira ile Nigeria.

Awon enia ti o wa sibe, awon Oloye Ife ati agbegbe re, awon enia jankan-jankan ninu ile isin, awon Olugbimo ati awon eni pataki lati ibigbogbo.

# OMO NIGERIA TO NKOSE OKO OFURUFU



Eniti e n wo yi ni omo ile Nigeria Ogbeni L. G. Harry ti ilu Abonema, ni ile Ila-Orun Nigeria ti o lo ko ise oko Ofurufu nilu Oyinbo.

Ki o to lo silu Oyinbo, Ogbeni Harry sise nile ise Olotu ijoba nilu Eko, o si ti sise saju nile ise Alabojuto eko iwe nilu Kaduna, ile Ariwa.

# OLOTU IJOBA BA AWON ENIA ILU KAMARU SORO

EKO — Olotu ijoba Apapọ ilẹ Nigeria Alhaji Sir Abubakar Tafawa Balewa fi ẹrọ asọro-mag-esi ba i'u Kamaru ti apa isalẹ sọrọ lalẹ ọjọ Ọsẹ (Sunday) nipa ibo ti nwọn yio di ni ọjọ kọkanla oṣu Feburary ti o mbọ yi lati le fi mọ bi nwọn yio faramọ ilẹ Nigeria tabi ilẹ ti nwọn nso ede Faranse ni Kamarun.

Olotu ijoba bẹrẹ ọrọ rẹ bayi :- Mofẹ ba nyin sọrọ l'alẹ yi nipa ilu Kamaru ti apa isalẹ ki o le ye gbogbo nyin yeke-yeke irufẹ aye ti ijọba Apapọ ilẹ Nigeria wa ninu ọran na. Mo si ni ireti wipe ọrọ mi na yio de etigbo awọn ẹniti ibo wọn yio sọ bi igbesi aiye gbogbo enia, ki iṣe ti awọn enia ti o mbẹ laiye nisisiyi nikan, ati awọn iran ti o mbọ ti akoiti bi yio ti ri.



Nigbati ọsẹ meta si ẹ dibo lati fihan bi ẹ fẹ faramọ ijọba Apapọ Nigeria tabi ẹ fẹ faramọ ijọba adaduro ti Kamaru. Eyi jẹ ohun ti o je pataki ti ọpọlọpọ enia ko le ṣe ni gbogbo igbesi aiyẹ wọn.

Mo fẹ fi ohun ti yio ṣele han nyin bi ọpọ enia ba dibo lati faramọ ilẹ Nigeria, mo si tun tẹnumọ gbolohun yi wipe "ki ẹ tun faramọ" Nigeria nitoripe titi di oṣu October tokọja, a ti wa pọ fun ogoji ọdun ati fun bi ọdun mẹdogun tokọja ni aṣoju ilu Kamaru apa isalẹ fi ṣe iṣẹ ribiribi ni nu ijọba ilẹ Nigeria nipa wiwa ninu ile igbimọ Aṣofin akọkọ ati ninu ile igbimọ Aṣofin ti ijọba Apapọse ilẹ Nigeria, pẹlu ninu igbimọ awọn to mu opo ijọba dani.

Niba ṣoki, bi ẹ ba faramọ Nigeria lọna kini, ẹ mu ohun ti o daju ti o si duro ṣinṣin, ti o jẹ aye ọla nipa jijẹ ara iran nla ilẹ Afrika ti o mu ẹhinwa-ọla yin daju. Boribori gbogbo rẹ, a le mu nyin mọ daju pe abẹ ofin, idabobo ẹmi yin ati awọn ile si ọkọ yin, ati alafia fun gbogbo enia yin ni.

Bi ẹ ba faramọ Kamaru, ẹ ko le ni ireti lati wa ni alafia tabi idajọ ododo ti a ti pese fun yin titi di isisiyi. Dipo alafia ati irọrun, dipo afikun ilewe ati awọn ile iwosan eyiti ireti wọn daju ti ẹ ba tun faramọ Nigeria, gbogbo nkan wọnyi ni ẹo padanu.

Mo da ọrọ mi duro bayi, lẹkansi mo tun fi tinutinu mi kesi ẹnyin ara ilu Kamaru, paapa ti apa isalẹ wipe ki ẹ ronu yin daradara lori ẹhinwa-ọla tabi ọjọ iwaju.

O d'owurọ'o.

# OLOTU IJOBA IWO-ORUN LO BE ILU OFFA WO

IBADAN - Olotu ijọba Iwọ-orun Oloye S.L. Akintola dakan lọ bẹ ilu Ọffa wo ni ọjọ kejidi-lo-gun oṣu yi, o si lọ sile awọn ẹbi ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre (A.G.) ti o wa ninu ijọ Al tako nile igbimọ Ariwa, Ọgbẹni Olawọyin ti o mbẹ ninu ẹwọn nisisiyi. Nibẹ ni Olotu ijọba ti ba awọn enia rẹ sọrọ iwuri ti o siki wọn ku ilede ọmọ wọn.

Lẹhin na ni Olotu ijọba wa dori moto rẹ kọ ọna Ọyọ, nibiti o ti lọ fi abẹwọ rẹ ba Ọla fun Alaiyeluwa, Bello Gbadegẹsin, Ọba Alafin Ọyọ.


## OKU'JA WOLU

NIGBATI OJA KO BA TA, TI ENITI O NRA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI ṢE LE RA OMIRAN. EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE TI ỌJA RẸ YIO FI MA TA BI IṢU AKARA GBIGBONA.

**E polowo Oja Yin**
**Sinu Iwe Irohin**
**ELETI - OFE**

# ELETI--OFE

ANIUWON KO SE WI L'EKO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS

Lagos. "ELETI OFE, LAGOS"

P. O. Box 407 Phone 23370

VOL. XIII. NO. 682 SATURDAY JAN 28, FEB. 3. 1961.


## ALAFIA IGI NI ALAFIA EIYE

Alafia awon omo ekee ni alafia awon agba nilu ... alafia enia ti o ngbe inu ilu ni awon ... alafia ilu.

... dun gidigidi nigbati Apapo wa ... ya Ogboju Onisegun Dokita Gans fun itoju amodi awon omo ekee lati ilu Oyinbo, (Specialist in Children diseases) fun itoju awon omo wa.

Ohun ti o mu inu wa dun ni pataki julo nipe awon omo ekee ti ori ni yio pada di Opomulero ilu wa lehin-ola. bi Olorun ba da emi won si-benbe eyi ko le se dabi alara bi ko ba si Onisegun ti o ni imo yekeyeke nipa itoju awon omo wa. Nitorina, tokunrin-tobinrin wa ni o fi ope fun awon oluioko ti o mu opo ijoba wa dani.

Sugbon nigbati a gbo wipe Dokita Gans na se aipe lipiya re ti o ko sinu iwe irohin ti awon oluioko ijoba wa si pinnu lati yowo re kuro lowo itoju awon omo ekee, je ohun edun okan wa. Nitorina, awa Eleti-Ofe pelu awon iya wa ti nwon mbe ijoba wa fun atunro pada lori oro idaduro Dokita Gans, ki enyin Opomulero ijoba wa fi oju anu wo oro ebe wa na nitori awon omo wa, omo ekee, eje orun.

E darijin Dokita Gans.

## EMI K'OLE FI OLE JIJA SILE

ONITSHA — Okunrin Hausa kan ti oruko re nje Ibrahim Hasan ni o so fun adajo Kotu ilu Onitsha wipe ole jija ... se ... o si ti di baraku fun on, nitorina, on ko le fi ole jija sile.

Eniti nwon fi sun ... wipe o ji owo ... un marun ti ... kan. Ina A ... so fun adajo pe ... ma ... ko Kotu gofo, ki o se adajo ewon fun on.

Adajo-na si ewon osu mejila pelu ise agbara.

## OLAGUNJU JEBI IKU

Eko-Kotu nla tilu Eko ko ejo ele arotunro Shitta Olagunju ti Adajo John Bennet dajo iku le lori ni Kotu Asaisi ninu osu September odun to koja lori iku ti o pa egungun, Mufutau Bamgbose ni ojo kerindilogun osu April, ti odun to koja, ni Opopo Oshodi, l'eko.

Olagunju pelu awon enia meji ni nwon fi sun esun apania ki nwon to da awon meji na sile. Kotu gba wipe idajo na duro lori eri ti nwon je nigbati nwon nse ejo re, nitorina, o jebi iku.

## IGBIMO ATUNLUSE IJEBU-ODE

Ibadan – Ogbeni J. O. Adigun, ti ise Alase ile ati ile kiko ijoba Iwo-orun ti yan awon enia patakipataki ti yio je igbimo atunluse fun ilu Ijebu-ode.

Awon gbajumo enia na nwonyi:- Ogbeni Sogunro Pitan, (Alaga) Olola M. A. B Petuga, Oloye J. O. Oshinbogun, Oloye A. Onasanya, Ogbeni J. O. Badejo, Ogbeni O. A. Okeola, Oloye S. A. Olukoya Ogbeni Adekunle Kukoyi, Ogbeni Fasasi Lawal, Oloye Olatunji Kukoyi, Dokita Alabojuto ilera ilu tabi Asoju re, Alase ile kiko (Executive Engineer) ti ilu Ijebu-Ode tabi Asoju re ati Ogbeni T. A. Bello ni akowe won.

## Awon Soja To Farapa Mbo Wale

Awon Soja wa meta pelu Soja Oyinbo omo Gesi kan ti nwon farapa nigbati nwon figa-gbaga po pelu omo ogun Mobutu ni a gbo wipe nwon nko won pada bo wa sile.

Enikini ni Private Joseph Ndsa ara ilu Makurdi, enikeji ni Saji Momo Aji ara ilu Maiduguri, eniketa ni Mafiri Dong ara Ibadan.

Second Lt Malcolm Matthew, omo ilu Oyinbo Gesi. Nwon yio de titi ojo meta.


E ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe ti o kun fun Irohin Aladun

# Oloye Akintola Ni Alajela Koko Fun Awon Agbe

IDADAN - Minisita kekere ti Alabojuto Alafia ati Idaraya ilu Ibadan Oloye J. A. O. Ogunmuyiwa, ni o so wipe Oloye S. L. Akintola ti ise Olotu ijoba Iwo-orun nisisiyi, ni eni akoko ti o je asiwaju ti o ja fun owo Koko ile Nigeria.

Oloye Ogunmuyiwa so pe nigbati Oloye Akintola nko eko nilu Oyinbo niwon ogoji odun s'ehin ti o se isipaya meji ti o je pataki lori ise Koko. Oloye Akintola l'o fihan nigbana wipe nwon nta Koko ni igba ponun (£200) fun awon Amerika fun ekun iwon kan nigbati o je pe ponun meta-abo (£3 : 10/-) ni nwon nsan fun awon agbe fun okuta kan (per Cwt)

Gege bi eredi isipaya pelu atako ti Oloye Akintola tun se iye owo Koko g'oke lati ponun meta-abo si ponun meje-abo fun okuta (per Cwt).



Lati igbana wa ni Oloye Akintola ti nja fun awon agbe Olukoko nina egbe re, egbe Afenifere (Action Group).

Loni, ijoba Iwo-orun ti Akintola nse Olotuko re n o nsan owo ti o ga julo nile Afrika lati gbe ise awon agbe duro lori Koko.

Oloye Ogunmuyiwa tun so wipe ijoba Iwo-orun nwa ona, nisisiyi ti yio f gba awon agbe kuro lowo awon olowo-ele






# OLOYE AWOLOWO FI AGA-OLA TA IGBIMO LORE

oo oo oo

IKENNE — Asiwaju Ijo Alatako ninu igbimo Apapo ati Olori egbe Afenifere (Action Group) Oloye Obafemi Awolowo ni o fi aga-ola kan ta igbimo Ijebu Remo lore, o si ko sinu iwe re wipe on ti gba ijoba awon omo ibile ilu Ijebu t o wa l'Eko ti nwon fi aga na ta on lore wipe on le lo si ona ti o ba ise.

Alaga Oba Awolesi Akarigbo Ijebu Remo ti ise Baba egbe igbimo ilu Ijebu Remo ni o fi ... na joko nigbati akowe igbimo so wipe o di lilo

Ninu ipade igbimo kanna ni Ogbeni ... ni won, Ogbeni J.D. Bullivant ti iwe ase wipe ki igbimo ... se ... won fanra won lati owo ijoba Iwo-orun le igbimo lowo.

Ninu oro ti Ogbeni Bullivant so ki o to fi iwe ase le igbimo lowo o ki won ku orire, ati awon Olu... ati awon oslse igbimo fun ase yege ise won ti o fun won ni iwe ase yi. Irufe iwe ase bayi ni nwon ma nfun igbimo ti o ba se ise re pelu ogbon ati lakaye ni ase yege.

Ogbeni Bullivant so wipe on ni ireti wipe igbimo ko ni ja ki ijoba ipinle k'abamo igba ela ti o ni si won.

# IJOGBON OGBA EWON

OWERRI — Awọn ẹlẹwọn ti nwọn fẹ ko lọ silu Okigwe lati silu ọgba ẹwọn ilu na, ni a gbọ wipe awọn ẹlẹwọn enia na kọ lati lọ.

Nigbati awọn olutọju ẹlẹwọn fẹ ko wọn sinu Moto nla pelu ipa, nwọn kọ, ibẹ ni ija ti bẹ silẹ. Nwọn nilati ranṣẹ lọ pe awọn ọlọpa, ṣugbọn ki ọlọpa to de ija ti gbojikan larin awọn olutukọ ẹlẹwọn (Warders) ati awọn ẹlẹwọn, ṣugbọn ẹnikẹni ko fi ara pa.

Awọn ogoji enia ti nwọn je awọn ti ọdun ẹwọn wọn gun ni nwọn nko kuro nilu Owerri lo silu Okigwe, nigbati awọn ọlọpa de ni nwọn to gba lati lọ, awọn ọlọpa ni o ko wọn lọ.

# Nwon Sa Alufa L'ogbe Lori Adura

GBEDE — Ile ẹsin awọn Aladura (Apostolic Church) ti o wa nilu Aiyegunlẹ Gbẹdẹ, ni a gbọ wipe o di pẹ-ntuka nigbati aṣiwere ọkunrin kan ti Alufa ngbadura fun fo kuro lori ijoko, o bẹ lu Alufa, o si fi ada ṣa lori.

Kia-nmasa ni nwọn gbe Alufa lọ si ile iwosan ilu Lokoja fun itọju. Ile Adura daru lọjọ na tobẹ ti ọlọmọ ko duro de ọmọ rẹ nigbati olukuluku ndu ẹmi arawọn.

Ẹnyin ti ẹ nfi adura wo aṣiwere enia, ẹsọ di ọwọ nyin o.

## Jamba Oko Ofurufu Sele

Mexico — Ohun iyanu nla kan ṣẹlẹ ni ọjọ Alamisi ọse tokọja nigbati ọkọ ofurufu nla kan ti o ko ọpọlọpọ ero bi enia mẹrindi-ladọfa (106) gbe ... nile, ni kete ti o kuro ni ibudo, koiti ... jinna pupo ki o to farapa ṣugbọn ki o to gb'ina awọn enia bi mejile-logorun ti yọ ninu rẹ lai farapa.

Bi awọn enia ti ṣe yọ je iyanu fun gbogbo enia, ninu awọn ti o yọ na, awọn miran pada si ibudo ọgọ ofurufu awọn miran pada sile wọn.

Nigbati awọn Panapana de idi ọkọ ti o njona na, ko ṣe nkanmọ, afi igbati o jona kanlẹ fun ... rẹ.

LIVE WELL
EAT WELL
eat
"De FACTO"

OGBON ORI NI YIO SO!

Ọkunrin ti o ba le ṣe iṣẹ ọgbọn ori yio le ma gb'owo gidi nigbagbogbo.

O le ni ọdẹgbẹta ọmọ ilẹ Nigeria ti o ti kọ, tabi ti o nkọ lọwọ, awọn iṣẹ ọgbọn ori ni ile ẹkọ ti

The United Africa Company.

The United Africa Company of Nigeria Limited.

# ENIKENI KO GBODO LU ILU ISEDALE LAI GBASE

IJẸBU RẸMỌ -- Igbimọ ibilẹ ilu Ikenne ni Ijẹbu Rẹmọ ti iṣe ofin wipe ẹnikẹni ti o ba lu ilu Iṣẹdalẹ laigbawe aṣẹ lọwọ Baba ẹgbẹ igbimọ (President of the Council) ṣẹ si ofin sisan owo pọnun mẹdẹgbọn (£25) tabi ẹwọn oṣu mẹta.

Labẹ ofin ti Alaṣẹ Ijoba ibilẹ, Alhaji D.S. Adegbenro ti fọwọ si, ẹṣẹ tun ni pelu fun ẹniti o gbawe aṣẹ lati lu ilu Iṣẹdalẹ kan ti o balu orişi miran. Bakanna ni yio sanwo pọnun mẹdọgbọn tabi ẹwọn oṣu mẹta.

Ofin na tun sọ pe Baba ẹgbẹ igbimọ nikan ni ni o lagbara lati mọ ẹniti o le lu ilu Iṣẹdalẹ atị lori nkan ti nwọn le lu ilu na.

Igbimọ ibilẹ ka awọn ilu Iṣẹdalẹ na, ilu Gbẹdu, Balufọn, Obete, Agẹmọ, Oro tabi Oshugbo.

# AKOSILE EKINI NIPA ORO JESU

Lose yi oye katun te si waju si nipa awon Iwe.

OGBẸNI Bisọbu Papias nna asin tun sọ fun wa pe Mateu kọ gbogbo ọrọ ti Jesu nsọ pọ ni ede Aramatia, ede to jẹ wipe Jesu ati awọn ọmọ ẹhin nsọ. Ati pe nṣe ni ẹni kan kan ninu awọn to kọ wọn silẹ, gbiyanju gidigi i lati le tumọ awọn ọrọ na gẹgẹ bi wọn ti le sa agbara wọn to.

Awọn ọrọ Jesu ti Mateu papọ wọnyi ni ese odidi tia fi orukọ rẹ se apele rẹ. Ṣugbọn nṣe ni awọn akẹkọ lere pẹ, awọn ọrọ Jesu wọnyi, ati tete pa wọn lakọkọ bẹrẹ ati pe awọn ipapọ ọrọ na ni a npe ni Ọkiu, osi ni lati jẹ pe irufẹ akọsilẹ bayi ni Mateu papa nsọ nipa rẹ gẹgẹbi mo ti sọ tẹlẹ. Mateu kọ ako silẹ nipa ihin rere gẹgẹ bi Luku papa ti kọ tirẹ ati Maku akọsilẹ ti Mateu ati Luku kọ lati inu arọkọ Maku ni wọn ti wa. Eleyi si wa fihan ni pe lẹhin ti Maku ti kọ tirẹ ni awọn ti o ku ṣẹṣẹ kọ ti wọn.

Nitori na eyi tia kọ kọsilẹ ni lati jẹ pe ako wọn ni arin ọdun AD. 70 ati 85, ṣugbọn mo fe kie m daju pe awọn akọsile wọnyi si ti wa nile, (ewe) ni ọdun pupọ kia to bere si ko wọn jọ pọ gege bi akọsile ihin rere.

Ihinrere ti John ko farawe ti Maku tabi ti eni kankan. Oko si leto ma ro ero ti awon akeko na nro nipa re ti won nso pe Ihinrere ti John ko lati inu akojopo awon miran na. Pataki to wa nibe ni pe John ni igbekele ara re; nipa kiko ihin rere re gege bi ise awon igba ni.

# Faranse Tun Fe Dan Etu Oloro Wo

PARIS – Irohin lade nilu Paris wipe Faranse tun fẹ dan ẹtu Oloro wo nilẹ Sahara. Irohin na sọ wipe yio to oṣu mẹrin ki nwọn to dan ẹtu Oloro na wo ni ẹkẹrin ninu okun yanrin Sahara.

Fyẹi nwọn kọkọ danwo niti ọjọ kẹta'a oṣu February ọdun to kọja. Lẹhin eyi nwọn tun ti danwo lẹmeji, ti igbẹhin ni nwọn ṣe lẹhin ọdun Keresimesi.

(Wo yoku loju ewe kejo)

# Omo Eko Di Alufa Nilu Oyinbo



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Alufa Samuel Johnson ọmọ ile Nigeria ti o di alufa nile isin St. Martin-in-The fields ni gangi ategu Trafalgar ni ilu Oyinbo.

On ni a nwo ti Olori Agbọpa ni ile isin na ngbọwọ lọwọ rẹ yi.

KELVINATOR REFRIGERATORS

The Ideal Choice for the modern Kitchen





CAPACITY
4 6 cu. ft.
6 cu. ft
7 7 cu. ft.
9 4 cu. ft.
1 5 cu. ft.
H.P. TERMS
VAILABLE

Distributed by

LEVENTIS TECHNICAL

LEVENTIS

Available at Marina - Idde - Ibadan - Kano - Port Harcourt - Aba

and leading Department Stores


# FARANSE TUN FE DAN ETU OLORO WO.

(O bere loju ewe keje)

Bi a ti gbọ ọrọ na si ni pe Faranse nṣe aye titun kan ni oke Hoggar ni apa isalẹ Sahara nitosi Tamanrasset, nibiti awọn yio ti dan ẹtu oloro wo ninu iho ilẹ.

Ẹyiti nwọn ṣe gbẹhin lori ẹkẹta ni o m u i j ọ b a Nigeria fawe ajumọṣepọ wa ya pẹlu Faranse, ṣugbọn sibẹsibẹ, a tun gbọn pe nwọn tun nfẹ ṣe omiran.

## IKILỌ

Ni ilu Enugu ni atiebo wipe Olotu ijọba wa Alhaji Sir Abubakar Tafawa Balewa ti sọ wipe bi Faranse ba tun dan ẹtu oloro wo ni Sahara, ijọba ilẹ Nigeria yio ṣe ehun ti o to fun Faranse.

Eyi ni ẹsi ti Olotu wa fi si iwe ikini k'abọ t i awọn ọmọ ẹkẹk ile ẹkọ ogbon ori ti ki nilu Ẹnugu. Olotu ijọba wa sọ wipe nigbati Faranse ko b a ti bọwọ fun ijọba ilẹ Nigeria, ẹto ti wa ni ki a fi ohun ti o lo siwa han. O si dupẹ lọwọ awọn ọmọ akẹkọ fun pe nwọn fi ara mọ ajumọṣepọ wa ti ijọba w a fawe rẹ ya pẹlu ijọba Faranse.

# OJI NLA SO-DE KANRIN!

KABBA — Ojo n l a kan rọ ti o ṣe ọpọlọpọ jamba nilu Kabba ti agbegbe rẹ, o wo ọpọlọpọ ile o si ṣi orule ọpọlọpọ dau, ati ile isin Ijọ C.M.S. pẹlu.

Larin ọjọ mẹrin o fẹrẹ to ọgbọn ile ti oji ti faraba ni ilu Kabba a t i ni Iyara Ijumu niwọn ibuṣọ meje si Kabba.

Nigbati ojo na bẹrẹ, ko le rara, awọn enia nsare lọ si ile wọn ni ireti wipe bi awọn ba ti wọle, ojo ko ni pa wọn.

Ṣugbọn eyi ko jẹ bẹ, nigbati atẹgun bẹrẹ. ti o nṣi panu ori orule lọ igbadun k o s i ninu iyara wọn, bẹni ode gbangba ko ṣ e duro si, nitori awọn panu ile ti atẹgun ngbe fo kiri, ki o ma ba ṣe enia leṣe.

Atẹgun gbe awọn panu ile miran jinna t o idaji buṣọ. Awọn ile to faraba ju mejidi-logun lọ, ọpọlọpọ ninu wọn n i agbara ti ko lọ patapata.

Lẹhin ti ọjọ mẹrin ti eyi ti ṣe ni oji lile miran tun ja ilu Iyara Ijumu, o si ṣe jamba bakanna, o to i l e mẹwa ti eyi kan.

Lẹhin ti oji lile na dawọ d u r o, ni ijọngbọn miran bẹrẹ lori wipe emi l'o ni panu ile yi, i w ọ l'o ni, larin ilu mejeji, ariyanjiyan na bẹrẹ l o r i awọn panu ile ti o j i ṣ i lori orule i l e w ọ n, t i o ti dapọmọ arawọn ti enikan kole sọ wipe ti ile lagbaja ni eyi tabi ti ile tamẹdo ni.

# ASOBADE

Lati ọwọ M. Jaiveọ'a "F. A. ROUND FOUR"

| | | |
|---|---|---|
| 1 | Birmingham | Rotherham |
| x | Bolton | Blackburn |
| 2B | Brighton | Burnley |
| 2 | Hudd'field | Barnsley |
| 1 | Leicester | Bristol |
| x | Liverpool | Sunder[illegible] |
| 2B | Luton | Cardiff |
| | | Man c[illegible] |
| 1 | Newcastle | Stockpo[illegible] |
| 2B | Pete'boro | Aston Vi[illegible] |
| 1 | Scunthorpe | Norwich |
| 1 | Sheff. U'd | Lincoln |
| xB | Sheff. Wed. | Man Utd. |
| 1 | Southpton | Leyton O |
| 1 | Stoke | Aldershot |
| | | Shrewsbury |
| 2B | Swansea | Preston |
| 1 | Tottenham | Crewe |
| xB | Derby | Ipswich |
| 2 | Portsmouth | Middlesbro |
| x | Bournm'th | Southend |
| xB | Bradford c. | Port vale |
| 1 | Colchester | Brentford |
| xB | Grimsby | Watford |
| 1 | Hull | Tranmere |
| x 1 | Newport | Swindon |
| 1 | Notts c. | Chestfield |
| 1 x | Q.P.R. | Bury |
| 2 x | Reading | Halifax |
| x | Carlise | Barrow |
| x 2 | Darlington | Oldham |
| 2 x | Doncaster | Northpton |
| 2 x | Hartlepie's | Bradford |
| 2B | Mansfield | Accrington |
| xB | Rochdale | Millwall |
| x 2 | Southport | Work'gton |
| 2 | Wrexham | Gillingham |
| 2 | Charlton | Arsenal |
| 2B | Leeds | Everton |
| 1 | Allao | E. Stirling |
| x 2 | Berwick | Dunf'mline |
| 1 | Clyde | Hibernian |
| 1 | Dever'va'e | Stirling'a. |
| 2B | Elging | Airdrie |
| 1 | Falkirk | Celtic |
| 1 | Hearts | Tarff |
| 2 | Keith | Eastf.fe |
| 1 | Montrose | Albion r |
| 1 x | Q. Of South | S. Johnst'ne |
| xB | Queens P. | Arbroath |
| 1 | T. Lanark | Stenh'muir |
| 2B | St Mirren | Rangers |
| 1 | Cowd'nb'th | Hamilton |
| x | Morton | Dumbarto |
| 2B | Dundee U. | Dundee |

# Olotu Ijoba Apapose

(O bẹrẹ loju ewe kini)

Awon Minisita ijoba mẹta pẹlu awon Minisita kekere meji ni o ba Olotu wa lo.

Irohin iyẹsi won ko lẹgbẹ nilu Ẹnugu.

## OWE

**Ori L'onise, Eda Niwa. Enia Kodabi Allah, Oluwa Nipe K'oyeni.**

Printed & Published By The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370